**Owe**

Adię iba f'ọkọ, ba f'atitan se okan. Imado iba se bi ẹlẹdẹ i ba'lu jẹ. Eru iba f'ọba, enia ko ba ti ku ọkan.

# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

**Asoje**

Enia nia jeki t'enia sunwọn, t'eni na sunwọn ko ni gbo. Apa ọmọde ko le ka igi Ọse, yio ma doyika.

VOL. XIII No 695 LAGOS. SATURDAY JUNE 24, – JUNE 30, 1961. KỌBỌ MEJI (2D)

# ADAJO DA AWON AGBAGBA MEJILA (JURYMEN) SILE LORI EJO APANIA TI NWON MBA AWON SAINIS RO.

Eko— Ninu Kotu Asaisi ni ọjọ Tuesday ọsẹ yi ni Adajọ da awọn Agbagba ọjọgbọn enia mejila ti nwọn yan lori ẹjọ apania ti nwọn mba awọn ara ilu Ṣaina mẹrin ro lori iku Rahimi Yusuf ninu ọkọ oju-omi ti o ti nṣiṣẹ ni Apapa.

Ohun ti Adajọ fi da awọn Agbagba mejila na silẹ ni wipe nigbati Kotu rojọ tirẹ tan, ti Lọya awọn ọdaran na ti sọ wipe on yio pe awọn ẹlẹri wa jẹri, ni Adajọ fi dide wọle lọ.

N'gbati Adajọ pada jade wa s'ori aga idajọ ni Aṣiwaju awọn Agbagba ọjọgbọn mejila ti o ti ngbọ rọ ẹjọ na, Ọgbẹni S. A. Dabor dide sọ fun Adajọ wipe "gbogbo wa ti gba be awọn Alafisun ko ṣe alaye ẹjọ apania gẹgẹbi ẹsun wọn, a fẹ ki ojuwa mi tọ wa s'ọna,,.

Gbolohun yi gbe Ọga Agb'ejọro ijọba dide lori ijoko rẹ, o sọ wipe iṣẹ ti Kotu ni lati sọ bi ẹjọ wa tabi kosi, niwon igbati ọdaran ti sọ wipe on yio pe ẹlẹri, awọn Agbagba ọjọgbọn ko ni ẹtọ lati sọ pe ko si ẹjọ ninu afisun na.

Ọgbẹni Adajọ Dickson sọ wipe Kotu ti tẹle ofin nigbati o ti bere ki awọn ọdaran na ba fi pe ẹlẹri ti nwọn ... ti gba b, nitorina, ero ti awọn agbagba mejila (Jurymen) tako ero ti on, atipe nwọn nii ti jẹki nwọn ro'jọ boya ọrọ nwon le yi ẹjọ na pada. Ọrọ koiti kan wọn lati ṣe idajọ tiwon, nitoribẹ, on da gbogbo wọn si'le kuro ninu ejo na.

## Gomina Agba nlo silu Oyinbo

EKO - Gomina Gbogbo-gbo ati Alaṣẹ pataki ilẹ Nigeria Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe yio fi Eko silẹ ba ọkọ oju-omi lọ silu Oyinbo ni ọjọ Atalata (Tuesday) ọsẹ ti o mbọ fun isimi asiko diẹ.



Ọlọ̀ lẹ iyawo re, Iyafin Flọra Azikiwe, yio fi ọjọ kan siwaju e lọ. Niwọn iba asiko ti Gomina Agba yio fi ọjọ kan tiwaju rẹ lọ. Niwọn iba asiko ti Gomina Agba yio lo nilu, Oyinbo lọhun, ni nwọn yio fi bura gẹgẹbi ọkan ninu awọn Igbimọ Ab'Ọbajiro.

**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA.
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA
ILARO, BENIN-CITY, WARRI
SAPELE ABA KANO, ZARIA, JOS
LONDON OFFICE
15 THROGMORTON AVENUE, E. C. 2
Manager : F. O. Tyrrell.
Telepone : London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbandger London
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.

# Enito Fe Pa Obinrin Re W'ewon

SAPẸLẸ - Ọkunrin kan ti nwọn npe ni Owhiyine Enivbena ara ilu Isobo ti o nsiṣẹ akọpẹ, ni nwọn ju s'ẹwọn ọdun marun nilu Sapẹlẹ fun ẹsun wipe o gbiyanju lati pa iyawo re, Taghashe Owhiyine ni ni Ọgbọnjọ oṣu September ọdun tokọja.

Owhiyine fi ada ṣa iyakakiri ara nigbati o wa l'oju orun lori ibu un ninu ile wọn ni abule Ngbone nitosi Sapẹlẹ. O ti kọkọ sọ wipe ibinu l'o mu on ṣe iṣẹ buruku na.

Owhiyine ro'jọ ni Kotu wipe iyawo na ti fun on ni o gun majele je nigbakan ri Onṣegun cudu kan wo on san. Lẹkeji, ti ikọ jedọjedọ tun ba on ja, on ṣakiyesi ewe tutu ninu ọbẹ ti iyawo na fun on jẹ. Ju gbogbo rẹ lọ, o tijewọ fun mi wipe on ti ni ọkunrin miran (sic), gbogbo nkan wọnyi ni mo fi fẹ fun ri isimi lara, nko ni ife lati pa.

Ninu idajọ re, Ọgbeni Adajọ J. A. Kester sọ wipe bi enia ba nja ko wipe ki o lọ yọ ada lati fi pari ija na. Adajọ s... siwaju pe on ni igbagbọ wipe ale ti obinrin na yan ni o fa sababi ijangbọn na.

Ninu Kotu kanna ni Ọgbeni Adajọ Kester ti ṣa Godwin Ogbogbo s'ẹwọn ọdun mẹwa fun ẹsun wipe o ṣe idiwọ fun ọlọpa ki wọn ma le mu, o si yinbọn fun ọlọpa ni Ọna Ogodo, nilu Sapẹlẹ ninu oṣu oṣu December ọdun tokọja.

---

# E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Fun Irohin Aladun

---

## Oku Enia L'oju Irin Oko Reluwe

MAKURDI- Nigba ti oku enia kan ti a npe gegebi Ibrahim Makinaki- atọkunrin Madam Ibeha Japan ... Alaga ẹgbẹ Ọlọmi (N.P.C.) ẹka tiwọn Makurdi. Nwọn ri ... re sa lẹgbe irin ọkọ T'enuwo lapa Gusu Keremi odo Benue ni Makurdi ni ọjọ ere.

Irohin ti a fi lo wọ gbọ wipe ọkọ R... se ti o nlọ si Enugu ni o te koja, sugbọn awọn ọlọpa fura wipe nwọn ti le pa ọkunrin na ki nwọn to wa gbe oku rẹ sọ sori irin ọkọ Reluwe.

---

## Kotu Da Abudatu Sile

IJẸBU-ODE - Abadatu Ayeni, abileko obinrin kan ti o ngbe 9, Ọpọpo Idẹpọ nilu Ijebu-ode ti nwọn fi ẹsun pe o ji owo adoje pọnun (£130) ti o jẹ ti ọkọ ti o ti nfẹ ri, Ọgbẹni Abdul Lawal ni Kotu da sile lẹhin o ma lọ lọ ni afafin.

---

bala ni ni nwọn a yan ni a Igbimọ ibile ilu Ilar...

Ni agbegbe kanna, enia meji'a ti o ti wọle laisi atako fun ẹgbẹ Afẹnifẹre (A. G.) sinu Igbimọ ibilẹ ilu Ẹgbado. Ijoko meji-lelọgbọn ni o ku ti nwọn yio dibo fun u.

Gbogbo ijoko ti o kuna ni ẹgbẹ Afẹnifẹre yi jijadu ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C) yio du mọkan-dinlọgbọn nwọn ti o da duro yio du marun

---

# NWON H ESO KAJU FUN GOMINA.

Galli— Nigbati Gomina Ila-orun, Ọlọla Sir Francis Ibiam lọ lẹ oko kaju so nilu Ayalli, awọn ọgẹgẹ ilo iṣẹ na fi idi eso Kaju ta lọrẹ



Lati ilu Ayalli, ni nwọn ti nfi eso kaju ni 'kọ mọto ak'ẹru lọ si Enugu, lati pin kakiri fun awọn Asọju Onigowo ti o nta wọn yika ipinlẹ La-orun.

# OKO OFURUFU JA LULE NI KANO.

Kano--Oko ofurufu ti awon Jamani kan ti o ko ęru nlo silu Kongo ni o ja lulę nigbati on fę gunlę nibudo oko nilu Kano, enia kan ninu awon mejo ti o nsisę ninu oko na ku bambam

Awon enia męfa ti o ku ni nwon ko lo sile Iwosan Nasarawa fun itoju lęhin ti nwon ti yo won ninu oko ofurufu na.

Irohin ti a tun gbo ni pe oko na nko ohun ija lo si ilu Angola ni, yio gba ilu Kongo koja asan ni.

## Idibo Ijoba Ibile Iwo-Orun

IJARO -- Enia metadinlogu ninu ęgbe Afenifęre (Actson Group) ti i o ti wole laini latako ati enia kan ti o da duro fun rare Ogbęni Amo Akinbode ti wole pelu Sugbon ęnikan na ti f'aramo ęgbę Afenifęre. Eyini o sęęmo ęgbę Afenifere ti o ti wo'le di mejidinlogun (18) laiko ti 'dibo fun Igbimo Ibile ilu Ijaro.

Ninu aye ijoko metadinlogun ti o ku, awon ęgbe Alakuko (N.C.N.C) yio jijadu mejila, awon enia ti o daduro yio du meje, egbe Afenifere yio jijadu gbogbo metadinlogun na. Ninu awon ti o ti wole laisi atako ni Ogbeni M. O. Akinode ti o je Alaga Igbimo ti nwon tuka wa, ati o Ijoye mo-

(Wo yoku leju ewe kefa)

## Ribadu Yio Be Ilu Kongo Wo

EKO - Alaşe idabobo ilu, Alhaji Muhammadu Ribadu so fun awon soja ti o nlo silu Kongo ati lo ropo awon Soja ti nwon fę da pada wale lohun wipe on yio wa bę won wo nilę Kongo laipę, ki on le f'oju ri bi nwon ti nşe lohun.



Awon ogun Soja 24 ati awon Soja 62 enia ti nwon nlo si Kongo ni nwon de s'Eko lati Kaduna ni ojo S tide.

Nigbati Alhaji Ribadu mba won soro ki nwon to wako o so ninu oro re wipe on nlo silu Oyinbo, India ati Ethiopia laipe yi, lati ri bi işe Şjati awon ti ri, bi o ba ti npada bo wa si ile, on ni ireti lati ya wa bę ilu Kongo wo, ki on le mo bi awon Şoja ile Niger'a ti nşe lohun.


Işe to dara!

Işe to dara pelu owo òya ti
kò tàsé lo nfun ènia ni iyì ati
igbesi aiye to layọ̀.

*O lé ni ęgbã męsan ara Nigeria*
to mbę lenu işe to fesemulę labę

THE UNITED AFRICA COMPANY

THE UNITED AFRICA COMPANY
OF NIGERIA LIMITED

REVO

Be Cool With
Revo Ceiling Fans



—IDEAL CHOICE FOR
OFFICE OR
MODERN HOUSE

Available in various models

Distributed by

LEVENTIS TECHNICAL

Available at

LEVENTIS Marina, Iddo, Ibadan, Kano, Kaduna, Jos, Port-Harcourt, Aba, and leading Department Stores

## NI IRANTI

BABA W.A. OLUFE OWON

Ologbe Adisa Shefi Oriola.

Enini o lo ji Olorun nipe ni

oSunjo o,u June, 1956

Awa omo re.

A GIFT FROM HEAVEN!



BAMWO BABY MIXTURE
OF EXCEPTIONAL VALUE IN PREVENTING SICKNESS, CURING FEVERS, COUGHS, MEASLES AND TEETHING AILMENTS.
ENSURES SOUND SLEEP.
PRICE 2/6 POSTAGE 1/

THE EGBA TRADING AHADAN
STORES, 144 DENTON STREET,
P.O. BOX 2 EBUTE METTA & BRANCHES

QRQ OLOTU

# Kadara ! Kini Nje Be ?

Gbolohun ede akole oke wosika wa ose yi je ede ti awa eda enia ma nso wipe ayanmo enia tabi akunleyan-i-ad'aiyeba omo enia l'ode aiye yi. Nipa be, igbagbo ogorq enia nipe ohun ko'un ti o le de ba e ni inu aiye yi yala ni rere tabi ni buburu, je kadara, ati wipe ko si ayipada fun enibo wipe ki il o ma le sele si i.

Lotito ni Kadara wa, sugbon iyato wa ninu igbagbo ti awa enia si kadara ni ododo pupo ni eyiti a ma nwo erawa fa, nipa ero buruku, tabi ife gbigb'ona ati fi se nkan ti akoro igbehin re wo. Nigbati a ba se ohun na tan, ti abey ri re ko si rogbo fun wa gegebi a ti nfe, nigbana ni ede oro Kadara ne nitoripe, ako ni fe so wipe airoru jinle wa ni o fa sababi re.

Ojulowo ohun ti awa gba wipe o nje Kadara ni ibiti o un ti nyo ati ibiti o ti nwo, ti ko si ayipada fun u. Lehin ise owo Olodumare ti iru eyiti a la sile yi, al'owofa wa ni o ko opolopo nkan ti a ko fe ba wa ti a npe ni kadara.

## Owe Akare-rin

Latiowo R. A. Akanbi Ariyo Alias Oriemope

1, Iduro kosi beni ibere kosi fun eniti o gbe omori odo mi
2. Agbo to fisu sodo l'edija s'le, bi beko, omori odo ko nlu iya re lasan.
3, Eni amori ibaku Amori alara ibako si Kanga Kokumo pein iya re si ma ku.
4, Alaja enu aja, o si fi e, oni omu, ase, koni salse, bi epe l'o nse, o mo ndan ?
5, Ja ewe opot ki ori ij:

Erun, Iwo Jawe s'enu ki ori ise ti odi nfi nwon se.

(Iyoku d ose t'ombo)

## ELETI-OFE D'ARABA

Always ask for
'DE FACTO'
the bread with the
appetising flavour

OKU'JA WOLU

NIGBATI OJA KO BA TA, TI ENITI O NRA OJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI SE LE TA OMIRAN EYI NI OGUN TI ONISOWO LE SE TI OJA RE YIO FI MA TA BI ISU AKARA GBIGBONA.

E Polowo Oja Nyin
Sinu Iwe Irohin
Eleti-Ofe

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 23, Kosoko Street P. O. Box 4056 or Phone 23270